“Ọlọhun, má ṣe sọ saare mi di òrìṣà

Lati ọdọ Abu Hurairah, ki Ọlọhun yọnu si i, ó gba a wá lati ọdọ Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a: “Ọlọhun, má ṣe sọ saare mi di òrìṣà, Ọlọhun ti ṣẹbi lé awọn ijọ kan tí wọ́n sọ saare awọn Anabi wọn di mọṣalaṣi”.

[O ni alaafia] [Ahmad ni o gba a wa]

Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, képe Oluwa rẹ pé kí o má ṣe sọ saare oun dà gẹ́gẹ́ bí orisa ti awọn eniyan n sìn nipa gbigbe titobi fun un ati fífi orí kanlẹ fun un. Lẹhin naa, Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, fún wa ní ìró pé Ọlọhun ti gbe ikẹ Rẹ jìnnà sí awọn tí wọ́n sọ saare awọn Anabi di mọṣalaṣi; nitori síṣọ ọ di mọṣalaṣi lè di ọna awawi lati jọsin fún wọn, ati níní adiọkan sí wọn.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3336

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee